**Lakaye Oro**

Yowo kuro ninu iwa buroku, mura si ise rere, nitoripe awojo alagabagebe yio tuka Ina yio si jo a g o abetele run.

Yago fun oti mimu Bila fun iwa pansaga Oru m b o, nigbati enikan ki yio le sise E ma kiyesi ara.



# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.



**Kere o!**

Aisemojuba Almanak ti odun 1962 ti jade. Tete wa ra tire Sile meji pere ni (2/) Ni eyo kan. Sile mejidilogun (18/) fun mejila.

Bore tabi ki o wa ra tire ni 86, Old Aroloya St. Lagos.



VOL. V No. 301 MONDAY SEPTEMBER 18 — SEPTEMBER 24 1961 KOBO MEJI (2d)


# OBINRIN KAN YIPADA, O SI DI OKUNRIN.

NGWO:- OMOKUNRIN KAN TI O NJE SAKADI TI O TI NGBE IGBORO ILU E N U G U FUN OPOLOPO ODUN TI OJU AWON OLOPA SI TI MO ILE ATI ONA RE LO JEWO NIGBATI OWO OLOPA TE E.

SAKADI, SO FUN AWON OLOPA WIPE, NITOTO OKUNRIN NI ON NSE, SUGBON OKUNRIN KO GBE ON RARA, NI ON BA LO RA OMU OYINBO IRUN ORI OYINBO, BATA OYINBO, TI ON SI RAN ORISIRISI ASO TI OYINBO ATI TI IBO.

Nigbati mo bere si lo aso bi obinrin ti mo si nse egbe obinrin ni mo to bere si ri owo ti mo si ri ise Typist se.

Emi a ma gba awon okunrin laye lati ma fi owo te mi li omu, sugbon nko gba ki n w o n ri ihoriho mi nwon rope mo nse igberaga, nwon fun mi ni ise se nitori ki nwon le ri ojurere mi.

Bikose wipe awon Olopa fura simi ni, ko si eniti o le mo pe nko nse obinrin. Nitoripe ti mo ba mura tan mo dara ju awon obinrin miran lo, e wa mi a si ma da awon okunrin lorun, nigbati nwon ba nte omu mi, nwon o si ma ku si ara. Okunrin na si mbe ni itimole nisisiyi.

## Oro ti Oloye Awolowo so nipa Owo Ilu

Orisirisi oro lo ti nsele nipa awon oro ti mo ti nso beti oloye Awolowo wi. Die ninu won ni a o fi enu ba ninu won, nisisiyi ti o je wipe ile Naijiria ti di Ominira, sugbon awon Ijoba ile wa tun nfe fi okun fun wa lorun gegebi ti Ijoba Gesi

Ekeji, o wa ninu ofin Ile wa pe, enikeni ni eto ti o ba ti pe on le se, sugbon awon enia wa nile Hausa so ofin yi di asan.

Eketa, ona bi enia ti se nselu, ko lo siwaju mo niha Ariwa ile Naijiria, ni lori pe asiwaju awon Oselu nile Hausa je okan ninu awon alase ile na, ko jeki ilosiwaju wa ninu ise Iselu wa.

Ekerin, nipa asise, Ile Naijiria ti bere si sun kuro nile Afrika, awon enia Dudu si rope, ohunkohun ti Ijoba ba si ti se, abe ge niyen, ko si eniti o gbodo bere pe ba wo lo ti se se be.


SPECIAL PAGES FOR 1ST ANNIVERSARY OF INDEPEDENCE OF NIGERIA

On request of our readers, this journal will be publishing a special pages which wil be on sale through our Nigeria on the 2nd of October for the 1st anniversary of Independence of Nigeria.

Traders, Mercantiles, and personalities who like to book for spaces in the special Issue Should Contract the:-

ADVERTISEMENT MANAGER
16, Banigbose Street, Lagos. Phone: 21985.


## Eto ti Ijoba se fun ajodun odun kan ti Najiria gba Ominira.

EKO:— Irohin ta siwa leti wipe, Ijoba ti se eto awon ohun gbogbo ti yio sele ni ojo ajodun Ile wa, 1st October 1961. Awon Ijo Musulumi yio ke tira Dalailu ni oganjo oru mojumo ojo Ajodun Ominira ile Naijiria (30th September 1961) Bakanna ni awon Kiriyo yio se adura akanse ninu ile isin Alagogo ni Ebute-Ehingbeti (Christ Church Chthedral) ni agogo mokanla oru si agogo mejila ojo (30thSeptember titi di 1st October 1961).

Ninu Isin oru yi Gomina agba yio wa nibe, Minister yio wa nibe, awon enia jankanjankan yio wa nibe, Oba yio wa nibe, ati awon Ijoye Ilu pelu, lehin Isin na awon Soja tabi Olopa yio fon fere won tobe ti ori gbogbo enia yio fi wule.

Nigbati ile ba mo Alhaji Tafa Balewa yio fi oro gbohungbohun ba gbogbo aiye soro ni agogo mefa owuro, lehin eyi gbogbo awon omo Ile Eko kekere ati giga, ati awon omo ile Eko nlanla gegebi University yio lo fi ara kan ninu ola nla won ni gbalasa Odan.

Nwon o si ile isura nibiti a gbe ti nfi awon ohun isedale wa pamo si, nibe ni olukuluku enia yio gbe lo se iranti ohun ti awon Baba wa gbekele nigba aiye won.

Lojo Monday ti ise ojo keji osu October 1961. Isinmi yio wa fun Ijoba Onisowo ati awon onikongira, ki olukuluku le gbadun emi re.

## Ogun ile Kongo kuro ni kekere, o se ndi nla

KONGO:- Ija be sile larin awon omo ogun ile Kongo ti o mbe ninu Katanga pelu awon egbe Majeobaje (U. N.) ninu ija yi, o di ogosan enia to padanu emi re.

Egbe ogun ile Kongo pa ogbon ninu omo ogun Majeobaje awon Majeobaje ewe si pa adojo ninu awon ara ile Kongo.

Oniwe Irohin kan so pe, owo awon omo ogun Kongo nle si ogun na ni tori bikose wipe awon oyinbo kan to ko ara won jo ti nwon si gba ninu ara Kongo lati ma se Soja fun won ni won iba segun egbe Majeobaje.

Ninu ija na ogun pa awon Ogagun ara Sweden meji nwon si pa okan ninu omo ogun Majeoba ara ile India, ara ile Irish merin, ati ara Norway kan.

Ogbeni Jean B Kibwe ti ise okan ninu awon Minister ile Katanga ti gba leti fori pamo si abe Ijoba Majeobaje o si wa ni ilu Elisa betville.

# IWE SI OLOTU

## MA ṢE ṢI WA LỌNA, OGBẸNI SANNI ERIN

Olotu jọwọ gbami laye lati ṣe alaye fun Ọgbẹni Sanni lori iwe rẹ to kọ ni ọjọ kọtadilogun oṣu yi. Oju ewe keji. Anu ṣe mi lọpọlọpọ wipe biru Sanni ba lọ jẹ asaju, a ko ni sina ni Ibajẹ. Imado iba ṣe bi ẹlẹdẹ a ba lu jẹ. Ore kini ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe fun Igbomina, ṣe bi awọn ni Igbomina ripe ni Agannigan, Itumọ rẹ nipe, awọn enia wọnyi lo ko ogun ja awọn baba wa ni gba lailai. Kini o yapari lori to nmokun lodo, kini Ọgbẹni Sanni ri to tun fẹ ko wa lọ si oko Agannigan lẹkeji ki Oluwa gba ni lọwọ a fi ni leku lọwọ.

Mo fẹ ki Ọgbẹni Sanni ranti pe ogun Jalumi (Jalumi war) yọ lati kọ ẹ lọgbọn, awọn ogun ẹtan lo ku nisisiyi jibitu buruku, nitorina mo fẹ ki o ronu dada ki o to ma da awọn enia Igbomina bi ẹni nda ewurẹ, awa mọ ibiti awa nlọ o.

O tun jẹ ohun Iyanu lati ri pe ari tẹni kawi, a fi apadi nla de ure mọlẹ ni Ọgbẹni Sanni wa, Oniwe ara ti ko fi so Iya ti awọn ọmọ Iya rẹ njẹ ni Ile Ifẹ. oko Agannigan keji, nibiti iwe Afẹnifẹre di ohun aigbẹdọ ma ni ki o to wọlu.

Ha! Kiala! Afibi solore enia lo le sọpe kini Ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) ṣe, lẹhin ọda titi de Off-, Hospital ta gba ati Iṣegun to daju ati awọn nkan ba wọnni, kilo tun fẹ Ọgbẹni wa?. Mo bẹ ẹnyin Ọlọgbọn ọmọ Igbomina ati Oloye, ati Ọlọla gbogbo ẹnyin ti ko fẹ bọla nyin jẹ ki ẹ sa fun iru enia bi Sanni. Loni yi, ko si ẹgbẹ ti o ni otitọ ati anu, ati imọ Ọlọrun bi Ẹgbẹ (N. P. C) Olomi.

Emi ni Ọmọ Ibilẹ Igbomina
J. B. ỌLADIPỌ

## Esi oro Sanni Erin

LATI OWỌ K. ADE Ọmọ Oṣelu ki balujẹ
O BẸRẸ LATI ỌSẸ KEJI

Tabi Sanni Erin gbabọdi ni? o sọ ninu iwe rẹ pe A njẹ Ekuru ko tan ẹ tun ngbọn ọwọ rẹ si awo Eyi lo fi han ni kedere iru enia ti Sanni jẹ, laisi ani ani, Sanni Erin lati jẹ ọkan ninu awọn ti o ti wa ninu ẹgbẹ N. P. C

Ṣugbọn ti ko fẹ ki ọgbẹni Raphael Babaoye nipataki ati awọn ọmọ Oro ẹgbẹ rẹ na nitori idi pataki ti o ye wọn.

Ọgbẹni Sanni erin tun sọ ninu ọrọ rẹ pe igi kan ki i ṣe igbo; bẹni ni tolọ, ki i ṣe Ọgbẹni Raphael Babaoye nikan lo da ẹgbẹ yi silẹ bikoṣe ọpọlọpọ enia ti nfẹ ilọsiwaju Ilu Oro ati ti gbogbo Ilẹ Igbomina. Mo si ni Igbagbọ titi oṣn diẹ si gbogbo awọn ti o lodi si wa yio di ọrẹ wa. Emi ti mo nsọrọ yi ti gba iwe ọmọ ẹgbẹ o si to nkan bi ọtadin-nirinwo enia ti o ti gba ki enina to gba temi bẹ̀si ọpọlọpọ enia lo tun nkọwe siwa pe awọn fẹ wọ ẹgbẹ na ni ilu oro ati ni agbegbe rẹ. Bi ọgbẹ i Sanni Erin ko ba gbagbọ ni ọjọ ti a o ba ṣe ipade nla ti ajọdun yatọ si ẹyiti awa ma nṣe lọsọsẹ a o kede fun aiye gbọ, a o si ni ki ero ya wa wo. Nkan ti mo fẹ ki ẹyin ọmọ Ilẹ Igbomina ati gbogbo Ọmọ Oro mọ ni pe Ẹgbẹ ọdọ N. P. C. Igbomina. Eka ti Oro ti atida silẹ, ti asi kede siyin ninu oṣu July oṣu kẹsan ọdun yi jẹ ẹgbẹ pataki ti kole parọ lagbara Ọlọrun.

---

ADVERT 166

ADVERTISEMENT

The Ministry of Communications announces that a special set of postage stamps will be issued on the 1st of October, 1961, to commemorate the first Anniversary of Independence.

2. The issue will comprise of five values having the following designs:-

3d. - Armorial bearings of the Federation.
4d. - Map showing the natural resources Nigeria.
6d. - Nigerian Eagle.
1/3d. - Birds in flight.
2/6d. - Nigerians with the Nigerian Flag.

3. The Ministry will make avalaiable first day covers, which should prove to be attractive souvenirs of the occasion, at a cost of 5/- each.

4. Applications for these first Covers from persons resident in Nigeria should be forwarded to the Head Postmaster, General Post Office, Lagos. Each application should be accompanied by a remittence of 5/- for each Cover ordered, together with a typed addressed label not larger than 3" x 2" suitable for gumming on to the first day Cover. The envelope containing the application should be endorsed "First Day Cover" at the top left hand corner.

5. Applications for First Day Covers must reach the Head Postmaster not later than 25th of September, 1961.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE FUN ỌMỌKUNRIN GBOGBO TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIC

(MAJẸ AGBA O TẸ, ALEBI ELE EGBOGI)




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti aṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" yi bi o ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn mbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu

Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara Egbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe, ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru, bi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣe daradara to E-emi (breath) inu ko ba gunlẹ daradara to "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oke de adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju wipe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe konkọn nigbakugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu. Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere Egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADETUTU CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA. PHONE: 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

## EGBE IMOLE AIYE

Esu oro wa:- "IMOLE DE, OKUNKUN PARADA"

### A telewo eni ki tanni je!

Lati Owo:- FATAYI A. OYEROGBA (Bony Gasper)
The Prince College. Omo Egbe Imole Aiye No. 18.

Nigba laillai awon omodekunrin meta kan wa, won si je o m o ile eko kanna, aye kanna ni won jijo wa. Baba ekini je olowo, baba ekeji si je bale nilu won eyi eketa je omo asegita. Nigbagbogbo ti akoko bato lati ra iwe pelu aso ile iwe, omo talaka yi ni yio koko ri tire, sugbon awon omo meji toku yio ma yo Obi won lenu titi won yio fi ra tiwon. Ni ojo kan Oluko Agba ni ki awon Omode wonyi lo gba owo ikore. Awon olowo yi lo titi won ko si tete de, Omo talaka yi sure lo sile, o lo fo koloju re o mu owo nibe o si sure pada sile eko ki o ma ba padanu eko re, o si je iyalenu fun awon omo olowo yi won ba omo akuse yi nile eko o wse, ki Oluko to jekiwon joko o fun won ni egba mefa nitoripe won jafara.

Nigbati won jade isere won bere lowo omo akuse yi bi o ti se ri owo tire kiakia be, o si wipe "Atewo eni ki tanni je" sugbon owe ti omo yi pa ko ye won, won tun bi lere laise awada Ibiti o ti nri owo ni Irowo irose o tun fun won ni Idahun karna, Inu bi won fun oro re yi.

Okan si wipe bawo ni Atewo eni kise tani je? O si fesi pe nigbati eyino ba nsere emi a ma sise ti o le mu owo wa diedie, ti adie mi ba yin enyin emi a ma ta eyin re tabi ti omo re ba dagba emi a si ma fi owo yi pamo.
Nigbpti Baba mi ko ba ri owo fun mi mo ma towo bo apo temi lati se inawo kekere lori eko mi, awon elegbe re si wipe oro re wa. Otito ni pe Atelewo eni ki tan ni je.
Eyi ko awa Omo Ile Eko ti owa ni Egbe Imole Aiye lati mase dada si awon obi wa, ati lati mani ajeseku, eyiyi nipe ti won ba fun ni ni owo ki ama toju re, ki ama mano, ti anfanire bayoju, Nse ni enia ma dabi omo Olowo loju awon elegbe re, tabi ki won ni baba re lo fun tabi ki awon Apegan so pe o lo ji (Ole) won koni mo pe ise owo re ni.
O digba cee. e o tun ma gbadun mi ni ojo iwaju.

## Awon Omo Akeko Naijiria lo pade Awon Ara Lubeya.



Ijoba ile Naigiria lo fun awon eni merin ti a nwo wonyi ni a w o r a n lati lo je farji osu kan nilu awon Gesi nilu York ati ni Newcastle.
Bi nwon ti nje ilu kiri nwon se alabapade awon Scouts ara ilu Lubeya (LIBYA) nigbati nwon ki ara won tan, nwon wa mba ara won soro.
Oruko won ni wonyi: F. J. Dokumbo, Anthony Manuba, Binta Idiaro ati Veronika Oppia. Oyinbo ti o mba won soro ni Monsuru ati Wingrove.

## J. Modupe Johnson soro nipa owo Ifehinti fun awon Osise

Eyi ni eda oro ti Ololа J. M. J. so nipa awon Osise lojo ose ti o koja lo yi, o wipe fun nkan bi odun meta, ni oro ti nlo, ti o mbo larin Ijoba Alapapose awon Ijoba Ipinle, awon Onise ati awon egbe Osise nipa ohun ti o je nkan anfani fun gbogbo awon osise Ile Naijiria, oro na ni nipa ohun ti yio se awon osise ni anfani lehin ti nwon ba fi ise sile.



Iba ohun anfani ti o wa fun awon Osise nisisiyi ni pe, owo ti oga Ilese ndapada fun bi okan ninu won ba se si pade jamba lenu ise won, ki nwon gba owo die, bi a sen ko ba fun won laye lati ma ba ise niso, tabi bi obinrin Osise kan ba bimo, tabi owo isinmi lehin ise.
Nisisiyi I j o b a gbero lati da owo Ifehinti nla kan sile ti a npe ni (National Provident Fund,) Onise ati Osise ni yio ma d a w o yi, nitori ki awon Osise le ri ohun je lehin ti nwon ba pari ise won.
Ni apere, bi O s i s e kan ba ngba Pounun meta losu, Oluware yio ma da Sile meta sinu owo na, oga Osise na yio ma da sile meta pelu. Bi a ba da iye owo yi tan, Ijoba yio ma se isiro re, lati osu de osu, yio si ma lekun, ati elo ori re ni yio ma lekun, nigbati a ba siro owo ti o nda yi ni ododun ati e y i t i oga re da lododun fun ele ori re yio je sisi (six pence) lori poun kokan lododun.
Akoko ti awon O s i s e yio gbowo repete yi nipe:— (1) Nigbati ojo ori won ba di marundilogota. (2) Nigbati ailera ko ba jeki won le sise mo (3) Nigbati Osise kan ba njade lo kuro nilu ti ko pada mo. (4) Nigbati Osise kan ko ba ri ise se fun o d u n meji (5) Tabi osise ti o ba kun awon omo re yio gba owo re.

## Owe

LATI OWO:- M. A. YUSSUF Allah-Deh
No. 146 Omo Egbe Imole Aiye

Ika iba la, a ba Ilu je, Eru iba j ba enia koko. Kokoro to nje efo jare efo Olwonba ni eweko ndara mo. Bi a ba kuro ni Ilu kan a ki bere bi eko ibe yi tabi koyi. Aniuwon ko se wi lejo, Ija ilara ko tan boro. Enu Oforo ni paforo, ti o bi o m o meji to ni ile on kun sosose. Eniti o fi wadu -wadu ko aiye mo aiya, ti ko gbe je bo pe titi adi eni aiye nte kiri. ko to ki tuna se eyi, Omo Iya osi

# Iyawo dun losingin, Oko tun mi gbe



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni S. Talabi Falana, ti iṣe ọkan ninu awọn ogunna gbongbo ti o nṣe iṣẹ labẹ awọn Oyinbo Onipaṣiparọ (Royal Exchange Assurance) ni ebute ẹhingbẹti li Eko.

On li o fi iwe yi pe, ọpọ enia ninu awọn Ọrẹ ati ojulumọ lati fi tayọ-tayọ wa kara kun arisiki ọjọ igbeyawo ati isin ọmọ fun ọkọ ti awọn ọmọ rẹ ni ipari oṣu ti a wa yi (30th Sept 1961) ninu ile Isin ti a npe ni Saint Doninik ṣọṣi ni Yaba. Niwọn agogo mẹsan owurọ.

A o ṣe Isin igbeyawo ọmọ keji ninu ile Isin J ı h o f a Shalom. U. N. A. C a t h e d r a l ni Eko ni dede agogo meji ọsan. Lẹhin eyi gbogbo ẹbi, ara, ojulumọ, ati ibatan yio lọ si ile baba Iyawo ni No. 2, Adeṣina Street ni Onikẹ ni ita Yaba.

Ni aṣalẹ ọjọ na, Ọgbẹni Falana yio ṣe ase nla rẹpẹtẹ kan, nibiti ere ati ariya yio gbe sọlẹ, lati agogo mẹfa ırọlẹ. Ki Oluwa jẹki ọjọ na soju wa.


## Akiyesi pataki

### Sengovan Tablets! Sengova Tablets!!

(EXTRA STRONG FOR AGED MEN.)

SENGOVAN Tablets: Jẹ ajidewe fun awọn agbalagba ati Ilera gọgọbi ọmọkunrin.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti ilu Western Germany. Fun arẹ ara ẹniti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40: 80. years.)

SENGOVAN:- Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbalagba Ilu Jamani, ki ato ṣe amuwa rẹ si ilu Naijiria. Ajẹ bi idan ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere. a o ri lọwọ awọn Oniṣegun (Doctors) Naijiria tabi lọwọ alagba wa Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES. 26, BISHOP STREET. LAGOS PHONE. 23745. DIRECTION: 1 to 2 Pills is sufficient for your constitution, if so, do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.


# Okere ti bo iru mo Ode lowo, Ogbeni M. Opara ta a ti loke Oya

Lati Ẹnu:- OLOYE SAMUEL L. AKINTỌLA

O binu gbe Ibọn jẹ, erin wa wo si loke Amilala.

Oloye Akintọla sọ wipe Ọgbeni Ọkpara kore pupọ si ipo ti nwọn gbe si, ko lọgbọn to ẹniti o le wọ Bata ti asiwaju rẹ bọ silẹ, ọna bı nkan yio ṣe bajẹ lo nwa kiri.

Gbọngbọn kan ko si ayafi ẹniti o ti ara rẹ, Dr. Opara ti sin ẹgbẹ Alakukọ dẹ inu iparun. Nwọn ti tẹ ẹ baṣubaṣu ni Oke Ọya, nwọn si ti fọ loju, o wa ku bamu bamu si ilẹ Yoruba.

Ẹgbẹ A l a k u k ọ ti sọ ara won di kekere nilu, nibiti nwọn gbe nfẹ wọn, ṣugbọn nisisiyi nwọn ti tẹ lọwọ ẹniti o fẹran won Oloye Akintọla sọ wipe, nkan ti Opara fẹ ṣe niyi kı o to fi ọrọ ti waya boju pe awọn ara ipınlẹ-Iwọ Orun ti di arufin.

Ko nṣe isisiyi ni Opara ti nṣe keta rẹ, ko si ohun ti ko ṣe tan nitori ki a le pa Ijọba Iwọ Orun rẹ, diẹ loku igi gangaoran fẹrẹ le gun Ọrun loju Nigbati o ri wipe on ta a ti, lo wa da ọgbọn ti o da, Ẹnyin ara! njẹ ẹ rope o le sọ iru ọrọ bayı si Sadauna Ṣokoto.?

Ko si ọna ti Ọdẹlẹsinrin na ko gba tan, ki o sa le ti pe iṣokan wa bajẹ. Ẹ ma kiyesi iwa ọkunrin na, o nfẹ da rugudu silẹ ni, ohun ti nsọ fun awọn enia rẹ ni Ipinlẹ Ila Orun nipe Ki Ọlọmu da Ọmu Iya rẹ gbe, ki Hausa wa nilẹ Hausa, ki Ibo wa nilẹ Ibo, ki Yoruba fowọ mu ti wọn. Gbogbo ero Opara nipe ki ajumọse wa ma sa bajẹ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN PE NI:-

## RICHALET FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yatọ patapata si awọn RọbiRọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti wọn npota ni ilẹ yi.

Gẹgọbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ojulowo egbogi atata ti a nranṣẹ fun tita lati awọn ilu J a m a n i Faranse ati ti awọn Tatabulu Itali jẹ. Mọdaju wipe bi Ejẹ Ara ko ba mọ daradara awọn amọdı tabi ailera wọnyi le ṣe ọ Laku r e g b e orişişi Inarun, Ojuşişu tabı didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Ayadidun Itanpara, ekuru lara.
Ara riro, LapaLapa Egbo ẹ s ẹ, Amodi Apo ileitọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Rışaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ ara rẹ mọ tonitoni pẹlu Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ daudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun lomiran pẹlu nigbakugba.




Bere egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

OBẸRẸ LATI OJU EWE KARUN.

Ki ọlọmu da ọmu iya rẹ gbe, owo ti nwọn ba ri ninu epo mọto ti nwọn nti wa ninu ilẹ wọn ledi ti wọn nikan.

Ile ni a ti nko eṣọ rode, Dr. Opara papa ko jẹ gba wipe ki ẹnikan ba on da kebekebe. Ialigba ti o ti de ipo ti o wa yi lo ti bẹrẹ si ṣe ilara iru ipo ati Ọla ti Olọrun fun Ijọba Iwọ Orun.

Nṣe lo njijadu ki darudapọ le wa nilẹ Yoruba bikoṣepe enia jẹjẹ ati oniwa tutu ni awọn ara Benin nkan na iba ti bajẹ. Nilẹ Yoruba 3,0 1 3 ni iye awọn arufin tabi Elẹwọn, Sugbọn ni ilẹ Ibo 6, 164 ni awọn arufin ẹlẹwọn ti nwọn ni.

Iwọ Abanijẹ, ti ẹnikan ko ba ọ jẹ, sa ma ba nijẹ nlso nigbati iwọ ba dẹkun a ti ma ba ni jẹ, nigbana ni a o dide si ọ, ti a o si ba ọ jẹ.


# PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, Alefọ. Egbo ẹsẹ orisirisi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adaijino egbo, Ekuṣẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu, Akọ Inarun ati orisirisi arun "ARA" ọmiran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi k o k o r o titun ti awọn ara Ilu Tatanbulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wo l a r i n iiọ mẹta iwọ na yio ma rohinrẹ fun a w ọ n elomiran pẹlu. Egbogi ipara yi ki ṣe awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si ṣiṣẹ iye meji ninu rẹ eleyi si yatọ patapata si awọn ẹgẹrẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Orisi meji rẹ lowa, Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajẹbina PAYAL yi ni Sọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN SỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADEỌYỌ IBADAN


# Okunrin Aladura kan ku si eti Okun nibiti o nwa igi idana

Ọkunrin Aladura kan ti orukọ rẹ njẹ Johnson Ofunyadọnju ti nṣe adura fun awọn enia ni eti Okun Alasla li agbọ wipe o ku si ẹti Okun lẹnu lọwọlọwọ yi.

Bi a ti gbọ ọrọ na si niyi wipe, Owa ni Johnson tabi ẹniti o nwa enia tabi Oyinbo ṣọda si odo k e j i odo, ni New Lagos lo si ngbe ki o to walọ fiditi si eti okun ti o nsadura fun gbogbo enia.

Ni ọjọ kan ti otutu mu pupọ, ojade lọ wa igi ti y i o fi dana, jijade na ti ojade lọ wa igi idana, alọ ni a r i ako rẹ abọ. Akotakiji ni gbogbo ẹniti o ba ṣe kangẹ oku rẹ ni eti Okun, ko run Esinsin ko si kun awọn A g ẹ l i ti tẹsi afẹfẹ rere.

# Akiyesi

Enikẹni ti o ba ni ọrọ lati sọ nipa o h u n ti o ndun lọkan, tabi nipa ohun Iyanu ti o ri, tabi ti o ni imọran kan lati da ti o le ṣe ire ati anfani fun gbogbo enia, ki o ma mu wa, ẹ ko ni sanwo, si ọdọ Olotu Irohin Imọlẹ ni Eko.

OLOTU


# MOGBAYI COUGH MIXTURE

Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ orisirisi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, I k ọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arọ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan m i r a n ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu, Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d arapọ rẹ jẹ 24/-.)




**LILO RE:-**

Ọmọ oṣu mẹta...Idaji ṣibi tea kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila:- Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa:- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba ..............Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

9, Balogun Street West, Lagos, Nigeria. Phone 22515.

34, Docemo Street, Lagos. Phone 24247.



# KERE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyi n Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ. Eku afojuba egbogi pataki ti a ṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o sọpọ ni isisinyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ. TULU. LUKULUKE, OTUTU IGBA AIYA. ARA RIRO. ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO. Jọwọ danwo ajẹbina ni ogun yi. Irohin ko to afojuba.

Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin. O daju hanwun. E o ri iṣẹ rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ Oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23457
LAGOS


Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Banagbọse Street Lagos, Phone 21985. Olotu E. A. Adeniji 51, Tejuoṣo Street Suru-Lere YABA.

FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN
EKO:- Ṣile Mẹjọ ati Kọbọ Mẹjọ (8/8d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile mejila ati Kọbọ Mẹfa (12/6d)